

# Jẹ́ Ká Kàwé

Ìwé Akẹ́kọ̀ọ́

Kíláàsì 2

Sáà 1 — 3

Yoruba

USAID
FROM THE AMERICAN PEOPLE

THE INITIATIVE

# Jẹ́ Ká Kàwé

Ìwé Akẹ́kọ̀ọ́

Kíláàsì 2

Sáà 1 — 3

Yoruba

This early grade reading material for primary teachers and pupils in Nigeria is made possible by the support of the American people through the United States Agency for International Development (USAID) under The Initiative program (Contract Number AID-620-C-15-00002).

First edition, 2021

Rights and permissions

The text and illustrations in this work are licensed under the Creative Commons Attribution 4.0 International License. To view a copy of this license, visit http://creativecommons.org/licenses/by/4.0/. Under the Creative Commons Attribution license, you are free to copy, distribute, transmit and adapt the work as long as you attribute or credit the original author or illustrator. In the case of this book use the following attribution language: “Developed under the USAID funded The Initiative program and licensed under the Creative Commons Attribution 4.0 International License.”

---

Ìwé kíkà fún àwọn èwe tí a ṣe àgbéjáde rẹ̀ fún àwọn olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní Nàìjíríà wáyé pẹ̀lú àtilẹ́yìn àwọn ara Amẹ́ríkà nípasẹ̀ àjọ United States Agency for International Development (USAID) lábẹ́ ètò The Initiative (Nọ́ḿbà Ìwé-Àdéhùn: AID-620-C-15 -00002).

Àtẹ̀jáde kìn-ín-ni, 2021

Ẹ̀tọ́ àti Ìgbàniláyè

Àwọn ọ̀rọ̀ àti àwòrán tí a lò nínú iṣẹ́ yìí wà lábẹ́ ìwé-àṣẹ kárí-ayé ti àjọ Creative Commons Attribution 4.0. Láti ṣe àyẹ̀wò ìwé-àṣẹ yìí, ṣe àbẹ̀wò sí http://creativecommons.org/licenses/by/4.0/. Lábẹ́ àṣẹ àjọ Creative Commons Attribution, ẹ ní òmìnira láti ṣe ẹ̀dà, pín káàkiri, ṣe àgbéjáde, àmúlò tàbí àyálò lára iṣẹ́ yìí níwọ̀n ìgbà tí ẹ bá ti lè gbé oríyìn fún òǹkọ̀wé tàbí ayàwòrán ìpìlẹ̀ iṣẹ́ yìí. Láti gbé oríyìn fún ìpìlẹ̀ iṣẹ́ ìwé yìí, ẹ lo àṣàyàn gbólóhùn yìí: “A ṣe àgbéjáde iṣẹ́ yìí lábẹ́ àṣẹ àjọ USAID tó jẹ́ agbátẹrù ìnáwó fún ètò-ẹ̀kọ́ The Initiative àti lábẹ́ Ìwé-Àṣẹ Kárí-Ayé ti àjọ Creative Commons Attribution 4.0”

# Àtẹ Àkóónú

**Ìdúpẹ́** .................... **vi**
**Àwọn Òǹkọ̀wé** .................... **vii**
**Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ láti ọ̀dọ̀ Àjọ NERDC** .................... **ix**
**Ìfáàrà** .................... **xi**
**Sáà 1** .................... **1**
Ọ̀sẹ̀ 1 .................... 2
Ọ̀sẹ̀ 2 .................... 8
Ọ̀sẹ̀ 3 .................... 14
Ọ̀sẹ̀ 4 .................... 20
Ọ̀sẹ̀ 5 .................... 26
Ọ̀sẹ̀ 6 .................... 27
Ọ̀sẹ̀ 7 .................... 33
Ọ̀sẹ̀ 8 .................... 39
Ọ̀sẹ̀ 9 .................... 45
Ọ̀sẹ̀ 10 .................... 51
**Sáà 2** .................... **52**
Ọ̀sẹ̀ 1 .................... 53
Ọ̀sẹ̀ 2 .................... 59
Ọ̀sẹ̀ 3 .................... 65
Ọ̀sẹ̀ 4 .................... 71
Ọ̀sẹ̀ 5 .................... 77
Ọ̀sẹ̀ 6 .................... 78
Ọ̀sẹ̀ 7 .................... 84
Ọ̀sẹ̀ 8 .................... 90
Ọ̀sẹ̀ 9 .................... 96
Ọ̀sẹ̀ 10 .................... 103
**Sáà 3** .................... **104**
Ọ̀sẹ̀ 1 .................... 105
Ọ̀sẹ̀ 2 .................... 110
Ọ̀sẹ̀ 3 .................... 116
Ọ̀sẹ̀ 4 .................... 122
Ọ̀sẹ̀ 5 .................... 128
Ọ̀sẹ̀ 6 .................... 129
Ọ̀sẹ̀ 7 .................... 135
Ọ̀sẹ̀ 8 .................... 141
Ọ̀sẹ̀ 9 .................... 147
Ọ̀sẹ̀ 10 .................... 153

# Ìdúpẹ́

Àkójọpọ̀ àwọn olùkọ́ni àti àwọn amòye ló ṣe àgbékalẹ̀ ètò ìwé-kíkà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ yìí lábẹ́  ìtọ́sọ́nà àjọ Nigerian Educational Research and Development Council (NERDC) àti àjọ USAID tí ó ṣe agbátẹrù ìnáwó iṣẹ́ yìí fún àjọ The Initiative. A le rí orúkọ àwọn olùkópa iṣẹ́ yìí ní oju-iwe iii. Ọ̀jọ̀gbọ́n Ismail Junaidu, Ọ̀gá-Àgbà àjọ NERDC, ṣe àtìlẹ́yìn fún ètò yìí láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ títí dé ìparí. Denise O'Toole àti Dr. Nura Ibrahim láti àjọ United States Agency for International Development (USAID) ṣe àtìlẹyìn pẹ̀lú ìtọ́sọ́nà àti ìmọ̀ràn ní gbogbo ipele àgbékalẹ̀ ètò iṣẹ́ yìí. Ọ̀mọ̀wé Nurudeen Lawal, Lydia Ezihe Onuoha, Mark Hamilton, Zahra'u Abubakar Maishanu, Zaliha Nasiruddeen Bello, Joy du Plessis, Mary Sugrue, àti Corrie Blankenbeckler lo ìmọ̀ ètò ìwé-kíkà wọn láti ṣiṣẹ́ takuntakun fún àgbéjáde iṣẹ́ yìí. Àjọ SIL International ṣe àtilẹ́yìn fún àgbékalẹ̀ kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù tí a nílò láti ṣe ìtọ́ni fún kíkọ àwọn ìwé kikà titun náà nípa ṣíṣe àmúlò ọgbọ́n àtinúdá ti ìmọ-ẹ̀rọ Synphony. Ọ̀mọ̀wé Nasir M. Baba ni ó ṣàbójútó iṣẹ́ náà nígbà tí Ọpẹ́yẹmí Ogúnlẹ́yẹ ṣe ìpèsè ìlò ẹ̀rọ ìkànsí-ara-ẹni fún ìpàdé ìfọ̀rọ̀wérọ̀ orí ẹ̀rọ. Àwọn tí ó ṣe ìyàwòrán gíráfíìkì inú iwé náà ni Godwin Ondoma, Samson Lawrence, Christian Ikpe, àti Aliyu Sani. John Àkànbí Nhorj, Aliyu Sani, Ernest Ibe àti Uche Idu ni àwọn  aṣàpèjúwe àwòrán inú àwọn  ìwé náà.

# Àwọn Òǹkọ̀wé

| Orúkọ | Adírẹ́sì tàbí Orúkọ Ilé-Iṣẹ́ |
|---|---|
| Adeleye Timilehin | National Commission for Colleges of Education, Abuja |
| Adeosun Adetayo Joseph | Olabisi Onabanjo University, Ago Iwoye |
| Adepoju Folasade Funmilayo | Jagunmolu Girls' Senior Secondary School, Bariga, Lagos |
| Adeyemi Abiodun Adeyinka | University of Ibadan |
| Adigun Fatima Dasola | National Commission for Colleges of Education, Abuja |
| Aisha Bamanga | Universal Basic Education Commission, Abuja |
| Akinwande Olaide | Foursquare International School, Asero, Abeokuta |
| Alawiye Basheer Adisa | Lagos State University, Ojo |
| Audu Rosemary Busayo | Lagos State University, Ojo |
| Bakare Olatunji Babatunde | Michael Otedola College of Primary Education, Noforija-Epe |
| Bilyaminu Bello Inuwa | Bayero University, Kano |
| Bukola R. Adeleke | Ìṣẹ̀dálẹ̀ Media concept |
| Dámiláre Samson Oyèdélé | Yorùbá di Wúrà, Lagos |
| Daniel Abiodun Oluwafemi | No. 7, Abokanle, Street, Sekona, Ede |
| Dr. (Mrs.) Iyabode Deborah Akande | Obafemi Awolowo University, Ile-Ife |
| Dr. Margaret Lawani | Nigerian Educational Research and Development Council, Abuja |
| Dr. Mark Hamilton | The Initiative |
| Dr. Michael Olugbenga Ajileye | Alvan Ikoku Federal College of Education, Owerri |
| Dr. Oyedeji Victor Abimbola | Federal College of Education, Zaria |
| Dr. (Mrs.) Elizabeth Adebisi Banjo | University of Lagos, Akoka |
| Iyabode Baliquis Alaga | University of Ibadan |
| Lydia Ezihe Onuoha | The Initiative |
| Mary Ogbene Abah | Teachers' Registration Council of Nigeria, Abuja |
| Moses Ayọ̀bámi Oyèdélé | Yorùbá di Wúrà, Lagos |
| Mr. Aina Opeyemi | Nigerian Educational Research and Development Council, Abuja |
| Mrs. Babalola Victoria Olubanwo | Nigerian Educational Research and Development Council, Abuja |

| | |
|---|---|
| Mrs. Afolayan A. Funmilayo | Kwara State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Ipinlaye Omolola | Ondo State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Jumoke Fagbohun | Ekiti State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Kolade Bose O | Osun State Univeral Basic Education Board |
| Mrs. Ladipo Olaide | Oyo State Universal Basic Education Board |
| Mrs. Olayinka Ogungbayi | Ogun State Universal Basic Education Board |
| Nurudeen Lawal | The Initiative |
| Ojo Olubunmi Ayobami | The Bridge College, Abeokuta |
| Olayinka Phebe Olayemi | Federal Government College, Ijaniki |
| Omotoyosi Ishola | Camilla Brook Place School, Lagos |
| Opeoluwa Taiwo | University of Ibadan |
| Patience Abiodun | Lagos State Universal Basic Education Board |
| Prof. Oluyemisi Adebowale | Adekunle Ajasin University, Akungba-Akoko |
| Professor Solomon Olanrewaju Makinde | Lagos State University, Ojó |
| Rifqat Opeyemi Sanni | Adeniran Ogunsanya College of Education, Oto/Ijanikin |
| Sakiru Kazeem Adeniyi | Adeniran Ogunsanya College of Education, Oto/Ijanikin |
| Segun Adenipekun Olanibi | Aminu Saleh College of Education, Azare |
| Sulaymon Muhammad Raji | Adeyemi College of Education, Ondo |
| Zaliha Nasiruddeen Bello | The Initiative |
| Zahra'u Abubakar Maishanu | The Initiative |
| Olatunde Bamidele Eniola | Lagos State Universal Education Board |

# Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ

Ìmọ̀ ìwé-kíka ṣe pàtàkì fún àwọn ọmọde láti lè ṣe àṣeyege ní ilé-ẹ̀kọ́ àtí ní ìyókù ìgbé-ayé wọn lẹ́yìn tí wọ́n bá parí ẹ̀kọ́ wọn. Síwájú sí i, ìlànà ìkọ́ni ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé àti ìtọ́sọ̀nà tó péye ṣe pàtàkì jọjọ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè ní ìmọ̀ tí ó yè kooro nínú ìwé-kíkà, ní pàtàkì jùlọ láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ẹ̀kọ́ wọn. Àbájáde iṣẹ́ ìwádìí ni orílẹ̀ èdè-Nàìjíríà àti ní àwọn orílẹ̀-èdè mìíràn ti fi hàn kedere pé ìlànà ìkọ́ni àti ìtọ́sọ̀nà tó yè kòoro ló lè mú ìdàgbàsókè bá ìmọ̀ọ̀ṣe nínú ìwé-kíka àwọn ọmọdé láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ayé wọn. Ṣùgbọ́n ó ṣeni láàánú pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ní ìfàsẹ́yìn púpọ̀ nínú ìmọ̀ ìwé-kíkà. Ẹ̀yí ló mú kí àwọn àgbà-ọ̀jẹ̀ nínú ètò-ẹkọ jákè-jádò àgbáyé fẹnu kò láti gùn lé àṣeyọrí ètò ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà tí àwọn ìpínlẹ̀ mélòó kan ni orílẹ̀-èdè Nàìjíríà tí ń múlò. Àwọn ìgbésẹ̀ yìí ṣe pàtàkì láti lè mú ìlọsíwájú tó péye bá ètò ìkọ́ni àti ìkẹ́kọ̀ọ́ ní jáke-jádò orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Fún ìdí èyi, inú mi dùn láti ṣe àfihàn ètò tuntun tí a pè ní *Jẹ́ Ká Kàwé!* tí ó wà fún ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ (kíláàsì kìn-ín-ní títí dé ìkẹ́ta) ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní àwọn ìpínlẹ̀ tí wọ́n ti ń sọ èdè Yorùbá ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

Pẹ̀lú àjọṣepọ̀ gidi láàrin ìjọba àpapọ̀ àti àwọn ìjọba ìpínlẹ̀, pẹ̀lú ìnáwó tó péye láti ọ̀dọ̀ àjọ USAID, àjọ The Initiative Project ṣe àtìlẹyìn ńlá fún àgbéjáde àwọn ìwé kòṣeémánìí yìí láti mú kí ìkọ́ni àti ìkẹ́kọ̀ọ́ ìwé-kíkà ní àwọn ìpínlẹ̀ tí wọ́n ti ń sọ èdè Yorùbá ní ìhà gúúsù orílẹ̀-èdè Nàìjíríà le kún ojú òṣùwọ̀n. A dúpẹ́ gidigidi lọ́wọ́ àjọ *United States Agency for International Development (USAID)* fún ìrànlọ́wọ́ wọn èyí tí o mú kí àgbéjáde àkànṣe iṣẹ́ yìí wáyé, èyí tí ó sì fún wa ní ìdánílójú pé àṣeyọrí tó tẹ̀wọ̀n nínú ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà fún àwọn ọmọdé jẹ́ ohun tó ṣeéṣe.

Ètò tuntun tí a mọ̀ sí *Jẹ́ Ká Kàwé!* yìí wáyé ní àsìkò tí ó tọ́ tí ó sì yẹ, gbogbo ara ni a sì fi ṣe àtìlẹ́yìn fún ètò yìí. Láìṣe-àní-àní, ètò kárí-ayé ni ètò ìdàgbàsókè ìmọ̀ ìwé-kíkà fún àwọn ọmọdé, orílẹ̀-èdè wa Nàìjíríà kò sì kẹ̀rẹ̀ rárá nínú àtìlẹ́yìn wa fún ètò náà. Àgbékalẹ̀ ètò *Jẹ́ Ká Kàwé!* yìí tẹ̀lé àwọn ìlànà ìkẹ́kọ̀ọ́ káríayé tí ó dára jùlọ fún ìwé-kíkà, pẹ̀lú ìtọ́nisọ́nà, ọgbọ́n àti ìrírí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àgbà-ọ̀jẹ̀ onímọ̀ ìkọ́ni, onímọ̀ èdè Yorùbá, àti àwọn onímọ̀ kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù káàkiri àwọn ìpínlẹ̀ àti láti ọ̀dọ̀ ìjọba àpapọ̀ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Àgbékalẹ̀ àwọn ìwé yìí sì tún tẹ̀lé àwọn ìlànà ẹlẹ́rìí tó dájú fún ìtọ́nísọ́nà lórí ìwé-kika tí a ti lò pẹ̀lú àbájáde tó gbé ògo yọ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ní àwọn orílẹ̀-èdè mí̀ìrán káàkiri àgbáyé.

Àṣeyọrí ètò *Jẹ́ Ká Kàwé!* fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ yìí wà lọ́wọ́ àwọn olùkọ́. Àwọn ni agbátẹ̀rù àkọ́kọ́ fún àṣeyọrí ètò yìí. Ìmọ̀, ìfẹ́-inú àtí agbára wọn ṣe pàtàkì fún àbájáde ètò yìí. Nítorí náà, o ṣe pàtàkì pé kí gbogbo àwọn tí ọ̀rọ̀ ẹ̀kọ́ jẹ lógún fọwọsowọ́pọ̀ láti rí i dájú pé àwọn olùkọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ rí àtìlẹ́yìn tó péye gbà láti lè ṣe ìrànwọ́ fún àwọn ọmọ wa lórí ìmọ̀ ìwé-kíkà. Kí èyí le ṣeéṣe, àwọn olùkọ́ níláti máa ṣe ìtọ́nisọ́na àti àtìlẹ́yìn fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti mú ìwé-kíkà àti ìwé-kíkọ lóòrè-kóòrè bí iṣẹ́.

Àwọn òbí náà ní ipa pàtàkì láti kó nípa ṣíṣe kóríyá fún àwọn ọmọ wọn láti máa ṣe iṣẹ́ ìwé-kíkà àti ìwé-kíkọ láyè ara wọn nígbà gbogbo àti láti rí i pé àwọn ọmọ ń lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ lásìkò àti lójoojúmọ. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, àwọn òbi gbọ́dọ̀ rí i dájú pé àwọn ọmọ wọn ní ìfẹ́ sí ìwé-kíkà. Yàtọ̀ sí àwọn ọ̀nà ìkọ́ni tí olùkọ́ ń lò, ìfẹ́ tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bá ní sí ìwé-kíkà ni yóò ṣe atọ́kùn ìfẹ́ tí wọ́n máa ní sí ètò ẹ̀kọ́ ní gbogbo ọjọ́ ayé wọn, èyí tí ó sì máa ṣe okùnfà àṣeyege ní ilé-ẹ̀kọ́ àtí lẹ́yìn tí wọ́n bá parí ẹ̀kọ́ wọn.

Àwọn alákòóso ètò ẹ̀kọ́ ní gbogbo àwọn ìpínlẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá gbọ́dọ̀ rí i pe wọ́n ra ohun-èlò pàtàkì fún ìwé-kíkà yìí, kí wọ́n si rí i pé àwọn ìwé yìí dé ọwọ́ gbogbo àwọn olùkọ́, àwọn

akẹ́kọ̀ọ́ àti gbogbo ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ jáke-jádo ilẹ̀ Yoruba. Lára ojúṣe wọn sì tún ni láti rí i pé wọ́n n pèsè ètò ìdàgbàsókè-lẹ́nu-iṣẹ́ fún àwọn olùkọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ lóòrè-kóòrè. Èyí ṣe pàtàkì púpọ̀ fún àṣeyọrí ètò *Jẹ́ Ká Kàwé!* yìí. Ojúṣe gbogbo wa ni lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà yìí láti rí i pé ìpìlẹ̀ ètò yìí fẹsẹ̀ múlẹ̀ dáadáa fún ìlọ́síwàjú ẹ̀kọ́ àwọn ọmọ wa lóní àti lọ́jọ́ ìwájú. A tún rọ àwọn olùkọ́ lẹ́ẹ̀kan sí láti rí i pé wọ́n ń ṣe àmúlo àwọn ìwé yìí lójoojúmọ́ pẹ̀lú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọn. Èyí ṣe kókó fún ìdàgbàsókè ìmọ̀ ìwé-kíkà fún àwọn ọmọ wa. Tí a bá le gbé àwọn ìgbésẹ̀ pàtàkì yìí, ìdánilójú gidi wà pé ọjọ́ ọ̀lá àwọn ọmọ wa, ọjọ́ ọ̀la àwọn abúlé àti ìlú wa, ọjọ́ ọ̀la àwọn ìpínlẹ̀ wa àti ọjọ́ ọ̀la orílẹ̀-èdè wa yóò dára sí i.

**Prof. Ismail Junaidu**

Ọ̀gá Àgbà
Àjọ *Nigerian Educational Research and Development Council*

# Ìfáàrà

A ṣe àgbékalè ìwé yìí láti pesè ọgbọ́n àti ìmọ̀ tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ọlọ́dún mẹ́ta àkọ́kọ́ nílò fún kíka ìwé ní àkàyé. Ẹ̀rí tí a gbà láti ínú iyàrá-ìkẹ́kọ̀ọ́ ní ìhà àríwá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tí ó lè kàwé ní èdè abínibíbi kò tó nǹkan. Kódà, ìwádìí káàkiri àgbáyé fi ìdi ohun tí ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀-ìkọ́ni ti mọ̀ múlẹ̀ pé: Nígbà tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ bá lè kàwé jágaara pẹ̀lú àkàyé nínú èdè abínibí wọn, ló tó ṣe é ṣe kí irúfẹ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bẹ́ẹ̀ ṣe àṣeyọrí tó péye nílé-ẹ̀kọ́. Àwọn ìmọ̀ àti ọgbọ́n ìkàwé tí àwọn ọmọdé ti kọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ẹ̀kọ́ wọn yóò ran kíkọ́ ẹ̀kọ́ èdè mìíràn lọ́wọ́ bí ọmọ́ bá ṣe ń dàgbà sí i. Síwájú síi, ìmọ̀ àti ọgbọ́n ìkàwé fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ máa ń ran kíkọ́ ẹ̀kọ́ mìíràn lọ́wọ́ nínú èyí tí ìwé-kíkà pọn dandan. Láìdéènà pẹnu, bí ọmọ ṣe lè kàwé sí wà lọ́wọ́ irú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ọmọ́ náà gbà nínú yàrá-ìkẹ́kọ̀ọ́.

Àṣeyọrí èto ìwé-kíkà yìí wà lọ́wọ́ ìmọ̀, òye àti ọgbọ́n àwọn olùkọ́ tó ń kọ́ àwọn ọmọ nínú iyàrá-ìkẹ́kọ̀ọ́, àti ìfarajìn wọn láti jẹ́ kí àyọrisí rere bá ìwé-kíkà. Síbẹ̀, ìfarajìn tí ó lọ̀ọ̀rìn nípasẹ̀ ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn òbí àti àwùjọ. Ojúṣe àwọn òbí ni láti rí i dájú pé ẹ̀kọ́ kíkọ́ wáyé, pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti àtìlẹ̀yìn àwọn mìíràn tó wà ní àwùjọ ilé-ẹ̀kọ́. Ọmọ kọ̀ọ̀kan ni a gbọ́dọ̀ fún ní ìwé láti lè mú kí ìwé-kíkà wọn gbilẹ̀ sí i. Àwọn ọ̀gá ilé-ẹ̀kọ́ àti àwọn olùkọ́ gbọ́dọ̀ rí i dájú pé ìwé yìí wà ní àrọ́wọ́tó àwọn akẹ́kọ̀ọ́, kì í ṣe èyí tí à ń tọ́jú pamọ́ síbìkan láìlò. Ọ̀fẹ́ ni a gbọ́dọ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kí àwọn akékọ̀ọ́ lè ní ànfàànì níní àti lílo àwọn ohun-èlo láti lè yege. A gbọ́dọ̀ rí i dájú pé a gba àwọn akẹ́kọ̀ọ́ níyànjú láti máa mú ìwe wọn lọ sí ilé. Ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, ó ṣe pàtàkì pé kí àwọn òbí náà máa ran àwọn ọmọ lọ́wọ́ lórí àwọn iṣẹ́-àṣetiléwá, kí wọ́n rí i dájú pé ó yé wọn kí wọ́n sì ṣe é bó ti tọ́ àti bó ti yẹ. Àwọn òbí gbọ́dọ̀ máa kàwé tàbí kà ìtàn sí etí igbọ́ àwọn ọmọ wọn; kí wọ́n máa tẹ́tísílẹ̀ gbọ́ ohun tí àwọn ọmọ wọn ń ká fún wọn, kí wọ́n máa sọ ìtàn fún wọn, kí wọ́n sì máa ran àwọn ọmọ wọn lọ́wọ́ nínú àkọsílẹ̀ nípa ṣíṣe iṣẹ́ yìí lójoojúmọ́. Ìgbà yìí nìkan ni àwọn ọmọ lè yege bí wọ́n ṣe ń dàgbà sí i nínú ìmọ̀ àti ọgbọ́n àti láti ní ìfẹ sí ìwé kíkà - láti kàwé àti láti kàwé náà dáadáa.

A kọ ìwé tí à ń sọ nípa rẹ̀ yìí ní ìbámu pẹ̀lú èròńgbà pé gbogbo ará, ọ̀rẹ́ àtí mọ̀lẹ́bí ọmọ ló ní ipa pàtàkì láti kó nínú ríran ẹ̀kọ́ ìwé-kíkà ọmọ lọ́wọ́, pàápàá jùlọ ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀. Àwọn olùkọ́ àti òbí ló kó ipa tó ga jùlọ gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe là á kalẹ̀ níbí. Síbẹ̀, àwọn olùkọ́ àti òbí gbọ́dọ̀ mọ̀-ọ́-mọ̀ máa ṣe ohun tó máa mú kí ìkẹ́kọ̀ọ́ àwọn ọmọ gbèrú sí i. Ìwé yìí wà fún ìpìlẹ̀ tí a óò mọ lé; ó sì jẹ́ ohun-èlò tó ṣe kókó tí gbogbo ọmọdé nílò láti di olùfẹ́ ìwé-kíkà àti olúfẹ̀ ìkẹ́kọ̀ọ́ ní gbogbo ọjọ́-ayé wọn.



# Sáà 1
# Ọ̀sẹ̀ 1 - 10



Tara ra ata.

Tara ta ata.

Tara sebẹ̀ ata.

Tara jẹ ọbẹ̀ ata.

Ọbẹ̀ ata Tara ta.

| | |
|---|---|
| ■ | T t R r A a |
| ● | ta ra |
| ▲ | ata tata ara Tara |

## Ẹ̀kọ́ 1



| | | |
|---|---|---|
| ta | ta | |
| ata | ata | |
| tata | tata | |
| ara | ara | |



| | | |
|---|---|---|
| ta | ta | |
| ata | ata | |
| tata | tata | |
| ara | ara | |

## Ẹ̀kọ́ 2



Ata ta ara Tara.

Tara ra ata.



Tara fi ata ra ara.

Tara sebẹ̀ ata.



Tara fi ata ra ara.

Ata ta ara Tara.

Ata ara Tara ta Tara.

Tara wẹ ara.

Ara rọ Tara.

■ **T t R r A a**

● **ta ra**

▲ **ata ara Tara ra**

## Ẹ̀kọ́ 3



| | | |
|---|---|---|
| ra | ra | |
| ara | ara | |
| Tara | Tara | |



| | | |
|---|---|---|
| ra | ra | |
| ara | ara | |
| Tara | Tara | |

## Ẹ̀kọ́ 4



Ata ta ara Tara.



Tara fi ata ra ara.



Tàlà ra iṣu.

Tara àti Tàlà la iṣu.

Tara àti Tàlà ka iṣu lílà.

A ka iṣu lílà Tara àti Tàlà.

■ Ll Kk Àà

● kà là rà

▲ kàkà àkàlà Tàlà àkàrà

## Ẹ̀kọ́ 1



| | | |
|---|---|---|
| Kàkà | kàkà | |
| àkàlà | àkàlà | |
| Tàlà | Tàlà | |
| àkàrà | àkàrà | |



| | | |
|---|---|---|
| Kàkà | kàkà | |
| àkàlà | àkàlà | |
| Tàlà | Tàlà | |
| àkàrà | àkàrà | |

## Ẹ̀kọ́ 2



Kàkà Àkàlà Tàlà àkàrà



Tara ti Tàlà là iṣu.



Tàlà ra aṣọ àlà.

Tàlà ra ata tà.

Ata ta sí aṣọ àlà Tàlà.

Ara ta Tàlà.

Tàlà làkàkà fọ aṣọ àlà.

| | |
|---|---|
| ■ | Ll Kk Àà |
| ● | kà là tà |
| ▲ | Ààlà àlà làkàkà àkàlà |

## Ẹ̀kọ́ 3



| | | |
|---|---|---|
| Aàlà | Aàlà | |
| àlà | àlà | |
| làkàkà | làkàkà | |
| àkàlà | àkàlà | |



| | | |
|---|---|---|
| Aàlà | Aàlà | |
| àlà | àlà | |
| làkàkà | làkàkà | |
| àkàlà | àkàlà | |

## Ẹ̀kọ́ 4



Tàlà ra ata.



Ata ta sí aṣọ àlà Tàlà.



Tàlà ra ìwé alárà.

Àrà woroworo wà lára ìwé Tàlà.

Àrà ara ìwé Tàlà rẹwà.

Tàlà wá ra àkàrà.

Àrà ara ìwé Tàlà wu alákàrà.

**W w Á á O o**

**wo ro wá rá**

**àwo woroworo wá ará**

## Ẹ̀kọ́ 1



| | | |
|---|---|---|
| àwo | àwo | |
| woroworo | woroworo | |
| wá | wá | |
| ará | ará | |



| | | |
|---|---|---|
| àwo | àwo | |
| woroworo | woroworo | |
| wá | wá | |
| ará | ará | |

## Ẹ̀kọ́ 2



Tàlà ra ìwé dídà.



Àrà warowaro wà lára ìwé Tàlà.



Tàlà ra ìwé àtàtà.

Tárá wo ìwé Tàlà.

Tárá fẹ́ràn ìwé Tàlà.

Tárá lá àlá nípa ìwé Tàlà.

Tárá wá ka ìwé Tàlà kárakára.

**■ Ww Áá Oo**

**● wá lá tá**

**▲ àlá Tárá àwo**

## Ẹ̀kọ́ 3



| | | |
|---|---|---|
| àlá | àlá | |
| Tárá | Tárá | |
| àwo | àwo | |



| | | |
|---|---|---|
| àlá | àlá | |
| Tárá | Tárá | |
| àwo | àwo | |

## Ẹ̀kọ́ 4



Tárá ra ìwé àtàtà.



Tárá wo ìwé Tàlà.



Fọlá àti Tàlà lọ yàrá-ìkàwé.

Fọlá àti Tàlà ka ìwé.

Fọlá wo ajá.

Tàlà wo àga.

Ajá kò jọ àga.

| | | | |
|---|---|---|---|
| ■ | F f | J j | Ọ ọ |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ● | fọ | jọ | kọ |

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| ▲ | ajá | Fọlá | Jọlá | akọ | jọ |

## Ẹ̀kọ́ 1



| | | |
|---|---|---|
| ajá | ajá | |
| Fọlá | Fọlá | |
| Jọlá | Jọlá | |
| akọ | akọ | |



| | | |
|---|---|---|
| ajá | ajá | |
| Fọlá | Fọlá | |
| Jọlá | Jọlá | |
| akọ | akọ | |

## Ẹ̀kọ́ 2



Fọlá wọ ajá.



Fọlá àti Tàlà ka ìwé.



Jọlá lọ ọjà.

Jọlá ra ìwé.

Tárá wo ìwé Jọlá.

Tárá ka ìwé Jọlá.

Tárá fẹ́ràn ìwé Jọlá.

| | | | |
|---|---|---|---|
| ■ | F f | J j | Ọ ọ |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ● | jọ | fà | jà |

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| ▲ | ọjà | Jọlá | àjọ | awọ |

## Ẹ̀kọ́ 3



| | | |
|---|---|---|
| ọjà | ọjà | |
| Jọlá | Jọlá | |
| àjọ | àjọ | |
| awọ | awọ | |



| | | |
|---|---|---|
| ọjà | ọjà | |
| Jọlá | Jọlá | |
| àjọ | àjọ | |
| awọ | awọ | |

## Ẹ̀kọ́ 4



jọlá lọ ọjà.



jọlá ra ìwé.

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

**Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà**

**Ìpín 1: Lẹ́tà**

R l à W F j Ọ

**Ìpín 2: Sílébù**

Wá ta jọ là wo ra

**Ìpín 3: rọ̀**

Fọlá ara Tàlà Jọlá àwo Tata

**Ìpín 4: Àyọkà**

Tàlà ra <u>aṣọ</u> àlà.

Tàlà ra ata tà.

Ata ta <u>sí</u> aṣọ àlà Tàlà.

Ara ta Tàlà.

Tàlà làkàka <u>fọ</u> aṣọ àlà.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Irú aṣọ wo ni Tàlà rà?
2. Kí ni ó mú Tàlà ta ata?
3. Kí ni o lérò pé yóò ṣẹlẹ̀ tí Tàlà kò bá fọ aṣọ àlà tí ata ta sí?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

Àwo àkàrà ará ata

**Àríwísí Olùkọ́:**



Ire pa àtẹ.
Ire ta ẹja àti ata.
Adé ra ata àti ẹja Ire.
Adé se ata àti ẹja.
Ata àti ẹja Ire dára.

## Sáà 1 Ọ̀sẹ̀ 6 Ẹ̀kọ́ 1 àti 2

| | | | |
|---|---|---|---|
| ■ | E e | I i | Ẹ ẹ |

| | | | |
|---|---|---|---|
| ● | re | tẹ | ja |

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| ▲ | rere | Ire | àtẹ | ẹja |

### Ẹ̀kọ́ 1



| | | |
|---|---|---|
| rere | rere | |
| àtẹ | àtẹ | |
| Ire | Ire | |
| ẹja | ẹja | |



| | | |
|---|---|---|
| rere | rere | |
| àtẹ | àtẹ | |
| Ire | Ire | |
| ẹja | ẹja | |

## Ẹ̀kọ́ 2



Ire Pa àtẹ.



Adé se ata àti ẹja.



Tárá àti Ire lọ ọjà.

Tárá ra ẹja ní ọjà.

Ire ra ilá ní ọjà.

Tárá fẹja tọrẹ fún Ire.

Ire se ilá àti ẹja.

| | |
|---|---|
| ■ | E e I i Ẹ ẹ |
| ● | rẹ fẹ ti ja |
| ▲ | tọrẹ fẹja àti |

## Ẹ̀kọ́ 3



| | | |
|---|---|---|
| tọrẹ | tọrẹ | |
| fẹja | fẹja | |
| àti | àti | |
| ẹja | ẹja | |



| | | |
|---|---|---|
| tọrẹ | tọrẹ | |
| fẹja | fẹja | |
| àti | àti | |
| ẹja | ẹja | |

## Ẹ̀kọ́ 4



Tárá àti Ìre lọ ọjà.



Ìre se ilá àti ẹja.



Tárá lọ ọjà Iyì.
Tárá ra ata àti ilá.
Ìyá Tárá ra ìdì obì.
Tárá ra aṣọ òfì ní ọjà.
Ọjà Iyì ìlú Tárá dára.

| | |
|---|---|
| ■ | **D d Y y Ì ì** |
| ● | **dì yì yá** |
| ▲ | **ìdì idì iyì ìyá** |

## Ẹ̀kọ́ 1



| | | |
|---|---|---|
| ìdì | ìdì | |
| idì | idì | |
| iyì | iyì | |
| ìyá | ìyá | |



| | | |
|---|---|---|
| ìdì | ìdì | |
| idì | idì | |
| iyì | iyì | |
| ìyá | ìyá | |

## Ẹ̀kọ́ 2



Tárá lọ ọjà Iyì.



Ìyá Tárá ra ìdì obì.



Tárá àti Tàlà lọ ọjà.

Ìyá ta ẹja àti ẹyẹ ní ọjà.

Tárá àti Tàlà ra ẹja.

Ẹja ìyá dára.

Tárá àti Tàlà jẹ ọbẹ̀ ẹja.

| | |
|---|---|
| ■ | D d Y y Ì ì |
| ● | dá dì yá yẹ |
| ▲ | dára ìyá ẹyẹ ẹja yàrá |

## Ẹ̀kọ́ 3



| | | |
|---|---|---|
| dára | dára | |
| ìyá | ìyá | |
| ẹyẹ | ẹyẹ | |
| ẹja | ẹja | |



| | | |
|---|---|---|
| dára | dára | |
| ìyá | ìyá | |
| ẹyẹ | ẹyẹ | |
| ẹja | ẹja | |

## Ẹ̀kọ́ 4



Tárá àti Tàlà lọ ọjà.



Ìyá ta ẹja àti ẹyẹ ní ọjà.



Ọba ra ọ̀bọ.
Ọ̀bọ ọba wọ bàtà ọba.
Ìwọ̀fà ọba bọ́ bàtà ọ̀bọ.
Ìwọ̀fà ọba fi ọwọ̀ lé ọba.
Ọ̀bọ ọba rí ìwọ̀fà.
Ọ̀bọ ọba sá lọ.

| | | | |
|---|---|---|---|
| ■ | B b | Ọ̀ ọ̀ | Í í |
| ● | bọ | ba | wọ̀ | rí |
| ▲ | ọ̀bọ | ọba | ọwọ̀ | orí |

## Ẹ̀kọ́ 1



| | | |
|---|---|---|
| ọ̀bọ | ọ̀bọ | |
| ọba | ọba | |
| ọwọ̀ | ọwọ̀ | |
| orí | orí | |



| | | |
|---|---|---|
| ọ̀bọ | ọ̀bọ | |
| ọba | ọba | |
| ọwọ̀ | ọwọ̀ | |
| orí | orí | |

## Ẹ̀kọ́ 2



Ọba ra ọ̀bọ.



Ọ̀bọ ọba wọ bàtà ọba.



Tàlà ra ajá àti ọ̀bọ.
Orí ọ̀bọ Tàlà tóbi.
Etí ajá Tàlà tóbi.
Ajá Tàlà bí ọmọ.
Etí ọmọ ajá Tàlà tóbi.
Tàlà kọ́ ilé fún ọmọ ajá.

■ B b Ọ̀ ọ̀ Í í

● bí rí rọ̀ tí

▲ ẹbí orí ẹrọ̀fọ̀ ọ̀bọ

## Ẹ̀kọ́ 3



| | | |
|---|---|---|
| ẹbí | ẹbí | |
| orí | orí | |
| ẹrọ̀fọ̀ | ẹrọ̀fọ̀ | |
| ọ̀bọ | ọ̀bọ | |



| | | |
|---|---|---|
| ẹbí | ẹbí | |
| orí | orí | |
| ẹrọ̀fọ̀ | ẹrọ̀fọ̀ | |
| ọ̀bọ | ọ̀bọ | |

## Ẹ̀kọ́ 4



Tàlà ra ajá àti ọ̀bọ.



Orí ọ̀bọ Tàlà tóbi.



Ajá bàbá wọ kòtò lọ́jọ́ Ọ̀sẹ̀.

Ẹsẹ̀ ajá bàbá Tárá dọ̀tí.

Bàbá Tárá fọ ẹsẹ̀ ajá.

Ẹsẹ̀ ajá bàbá Tárá mọ́.

**S s M m Ẹ̀ ẹ̀**

**sẹ̀ mí sọ̀ dẹ̀**

**ẹsẹ̀ ọ̀sẹ̀ ẹ̀mí ẹ̀sọ̀**

## Ẹ̀kọ́ 1

| | | |
|---|---|---|
| ẹsẹ̀ | ẹsẹ̀ | |
| ọ̀sẹ̀ | ọ̀sẹ̀ | |
| ẹ̀mí | ẹ̀mí | |
| ẹ̀sọ̀ | ẹ̀sọ̀ | |

| | | |
|---|---|---|
| ẹsẹ̀ | ẹsẹ̀ | |
| ọ̀sẹ̀ | ọ̀sẹ̀ | |
| ẹ̀mí | ẹ̀mí | |
| ẹ̀sọ̀ | ẹ̀sọ̀ | |

## Ẹ̀kọ́ 2

Koríko kọ́ ẹsẹ̀ ajá.

Koríko kọ́ ẹsẹ̀ ajá.

Tàlá já koríko sílẹ̀.

Tàlá já koríko sílẹ̀.



Tàlà já koríko sílẹ̀.

Màlúù bàbá Tàlà jẹ koríko.

Koríko kọ́ ẹsẹ̀ màlúù.

Tàlà yọ koríko ẹsẹ̀ màlúù.

Màlúù fi ẹ̀sọ̀ ju ìrù sí Tàlà.

**S s M m Ẹ̀ ẹ̀**

**sẹ̀ mí mà**

**ẹsẹ̀ ẹ̀mí Ọ̀sẹ̀ ẹ̀sọ̀**

## Ẹ̀kọ́ 3



| | | |
|---|---|---|
| ẹsẹ̀ | ẹsẹ̀ | |
| ẹ̀mí | ẹ̀mí | |
| ọ̀sẹ̀ | ọ̀sẹ̀ | |
| ẹ̀sọ̀ | ẹ̀sọ̀ | |



| | | |
|---|---|---|
| ẹsẹ̀ | ẹsẹ̀ | |
| ẹ̀mí | ẹ̀mí | |
| ọ̀sẹ̀ | ọ̀sẹ̀ | |
| ẹ̀sọ̀ | ẹ̀sọ̀ | |

## Ẹ̀kọ́ 4

Màlúù fi ẹ̀sọ̀ jù ìrù sí Tàlà.

Tàlà já koríko sílẹ̀.

# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà

**Ìpín 1: Lẹ́tà**

ọ̀ ẹ d Y Ì m

**Ìpín 2: Sílébù**

bọ bi te rẹ yì wọ̀

**Ìpín 3: rọ̀**

ẹrọ̀fọ̀ iyì àtẹ ọ̀bọ ọ̀sẹ̀ ẹja

**Ìpín 4: Àyọkà**

Ọba ra ọ̀bọ.
Ọ̀bọ ọba wọ bàtà ọba.
Ìwọ̀fà ọba bọ́ bàtà ọ̀bọ.
Ìwọ̀fà ọba fi ọwọ̀ lé ọ̀bọ.
Ọ̀bọ ọba rí ìwọ̀fà.
Ọ̀bọ ọba sá lọ.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Ta ni ó ra ọ̀bọ?
2. Kí ni ìdí tí ọ̀bọ ọba fi sá lọ?
3. Kí ni ìdí tí ìwọ̀fà ọba fi fi ọwọ̀ lé ọ̀bọ?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

tọrẹ ẹbí ìyá rere

**Àríwísí Olùkọ́:**



# Sáà 2

# Ọsẹ̀ 1 - 10



Tàlà àti Tárá jí láààárọ̀.

Tàlà àti Tárá kí ìyá àti bàbá wọn.

Tàlà àti Tárá bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ilé.

Tàlà àti Tárá fọ aṣọ.

Bàbá fi owó ṣapala àti ṣàkì sílẹ̀.

Ìyá se ọbẹ̀ ṣàkì.

| | |
|---|---|
| ■ | Ṣ ṣ Ó ó É é |
| ● | ṣó lé wó |
| ▲ | aṣọ ìṣó ilé ṣàkì |

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2







Ọ̀rẹ́ ni Tárá àti Dára.

Dára wá sí ilé Tárá.

Tárá àti Dára ń ṣeré.

Wọ́n ṣe iṣẹ́ ilé.

Wọ́n jẹ ẹ̀wà elédé ní àjẹyó.

Tárá àti Dára bẹ̀rẹ̀ eré ṣíṣe.

■ Ṣ ṣ Ó ó É é

● ṣé wó dé

▲ ṣíṣe ṣeré owó ewé

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4







A rí Tàlà àti ajá ọ̀gá wa.

Tàlà po ẹ̀kọ fájá ọ̀gá.

Ajá ọ̀gá jẹ ẹ̀kọ tí Tàlà pò.

Ajá ọ̀gá fẹ́ràn ẹ̀kọ Tàlà.

Ajá ta abọ́ ní ìpá.

Ọ̀gá dúpẹ́ lọ́wọ́ Tàlà.

■ P p G g Ò ò

● pò pá gá gò

▲ àgò oge ga gogoro

## Ẹ̀kọ́ 1









## Ẹ̀kọ́ 2







Ọ̀rẹ́ ni Iyìọ̀lá àti ìyá Tárá.

Iyìọ̀lá ga ju ìyá Tárá lọ.

Iyìọ̀lá ga gogoro.

Iyìọ̀lá fẹ́ràn oge.

Iyìọ̀lá jẹ oyè Ìyá Oge Àwà.

Ìyá Tárá fẹ́ràn Iyìọ̀lá.

■ P p G g Ò ò

● gò gé pà pò

▲ àgò oge ga gogoro

## Ẹ̀kọ́ 3









## Ẹ̀kọ́ 4







Tàlà ra ìgò lọ́wọ́ Àdàmú.

Tàlà ra epo, ịṣu, àti gbúre.

Tàlà gbàgbé látí dé ìgò epo.

Epo dà sí aṣọ Tàlà.

Aṣọ Tàlà dọ̀tí púpọ̀.

Tàlà lọ fọ aṣọ rẹ̀ lódò Ọbà.

■ GB gb U u Ú ú

● gbọ́ gbà ṣu gbú

▲ gbàgbọ́ gbàgbé iṣu gbúre

## Ẹ̀kọ́ 1






# Ẹ̀kọ́ 2












Tàlà àti Tárá gbá àyíká ilé.

Tàlà àti ìyá rẹ̀ nu àga.

Tàlà àti Tárá fọ ilé ìyàgbẹ́.

Ooru mú nílé bàbá Tàlà.

Bàbá Tárá gbin òdòdó.

Ilé Tàlà àti Tárá dára púpọ̀.

■ GB gb U u Ú ú

● gbà pú ku

▲ gbá ọgbà púpọ̀ eku

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4







Onímọ̀ọ́tótó ni Tàlà.

Tàlà máa ń wẹ̀ déédéé.

Tàlà máa ń fọnu dáadáa láràárọ̀.

Tàlà máá ń fọ aṣọ àti ilẹ̀.

Tàlà máa ń fọ ahá àti agbè.

Onímọ̀ọ́tótó gidi ni Tàlà.

■ H h N n È è

● há hò gbè ni

▲ ahá ihò agbè Ọ̀ọ̀ni

**Ẹ̀kọ́ 1**





## Ẹ̀kọ́ 2







Bàbá Tárá pe ìpè nípa ìmọ́tótó.
Ó sọ pàtàkì títún àyíká ilé ṣe
Ó ní gbígbá ilẹ̀ ṣe pàtàkì.
Ó sì ṣe kókó láti máa wẹ̀ déédéé.
Fífọ ahá àti ìkòkò náà ṣe pàtàkì.

| | |
|---|---|
| ■ | H h  N n  È è |
| ● | pè  há  sè  ní |
| ▲ | ìpè  ahá  àsè  níbikíbi |

## Ẹ̀kọ́ 3









## Ẹ̀kọ́ 4





# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ______________________

**Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà**

**Ìpín 1: Lẹ́tà**

é p u Ò gb Ṣ

**Ìpín 2: Sílébù**

há gò ṣó pú wó gbù̀

**Ìpín 3: rọ̀**

gbàgbọ́ ẹyẹ ìṣó ìgò ahéré àsè

**Ìpín 4: Àyọkà**

Tàlà àti Tárá jí láàárọ̀.
Tàlà àti Tárá kí ìyá àti bàbá wọn.
Tàlà àti Tárá bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ilé.
Tàlà àti Tárá fọ aṣọ.
Bàbá fi owó ṣapala àti ṣàkì sílẹ̀.
Ìyá se ọbẹ̀ ṣàkì.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Kí ni Tàlà àti Tárá kọ́kọ́ ṣe nígbà tí wọ́n jí?
2. Kí ni ìdí tí bàbá fi fi owó sílẹ̀?
3. Kí ni ìdí tí ìyá fi se ọbẹ̀ ṣàkì?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

Dára, ipò, àsè, gogoro

**Àríwísí Olùkọ́:**



Orúkọ ẹṣin Tárá ni Onílù.

Ẹṣin Tárá wọ bàtà onírin.

Irun ìrù ẹṣin Tárá gùn púpọ̀.

Tárá fi ẹṣin sáré ìje.

Ẹṣin Tárá gba ipò kìíní.

Tárá gba àmì ẹ̀yẹ góòlù.

Inú Tárá dùn púpọ̀.

| | |
|---|---|
| ■ | IN in Ù ù UN un |
| ● | ṣin lù run kun |
| ▲ | ẹṣin onílù góòlù irun |

**Ẹ̀kọ́ 1**





# Ẹ̀kọ́ 2







Òmùwẹ̀ gidi ni Tàfá.

Tàfá máa ń wẹ̀ nínú òkun .

Olùkọ́ kọ́ Tàfá ní òfin ìwẹ̀ wíwẹ̀.

Tàfá fétí sí òfin olùkọ́.

Tàfá gba ipò kìíní nínú ìwẹ̀ wíwẹ̀.

IN in Ù ù UN un

fin mù kun lù

òfin òkun òmùwẹ̀ ìlù

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4







Tárá àti Dára ń gbá bọ́ọ̀lù.
Tàlà àti Dára mú apá kan.
Tàfá àti Tárá sì mú apá kejì.
Dára gbá bọ́ọ̀lù lu itan ràkúnmí.
Ràkúnmí ṣubú lu igi àgbọn.
Àwọn mẹ́rẹ̀ẹ̀rin fa ràkúnmí dìde.

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| ■ | AN an | ỌN ọn | ÚN ún | |
| ● | tan | fọn | kún | gbọn |
| ▲ | itan | ẹ̀fọn | ràkúnmí | àgbọn |

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2







Tàfá ní aṣọ ìṣeré mẹ́rin.

Dára láṣọ ìṣeré kan.

Àwọn méjééèjì ní aṣọ eré bọ́ọ̀lù.

Tàfá ní bàtà ìgbábọ́ọ̀lù kan.

Dára fún Tàfá ní bàtà ìgbábọ́ọ̀lù.

Tàfá náà fún Dára láṣọ ìṣeré kan.

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| ■ | AN an | ỌN ọn | ÚN ún | |
| ● | kún | wọn | bọn | ran |
| ▲ | ikún | àwọn | ìbọn | ẹran |

Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4







Tàfá wà ní ààrín Tàlà àti Tárá.
Iṣẹ́ ìlù lílù ni Tàfá ń ṣe.
Ìdílé onílù ni Tàfá ti wá.
Tàfá ń fi ìlù lílù dábírà.
Ọba fún un ní ẹ̀bùn pàtàkì.
Tàfá lùlù di olówó àti olókìkí.

| | |
|---|---|
| ■ | ÙN Ùn ÌN Ìn ÍN Ín |
| ● | kín rùn kùn sùn rín |
| ▲ | ọ̀kín ẹ̀bùn ẹkùn àìsùn ọrùn àárín |

## Ẹ̀kọ́ 1









## Ẹ̀kọ́ 2







Ọdẹ́rìndé jẹ́ akínkanjú ọdẹ aperin.

Ọ̀rẹ́ bàbá Tàlà ni Ọdẹ́rìndé.

Kò sọ́dẹ bíi Ọdẹ́rìndé ní Owódé.

Ó máa ń pa erin, ẹkùn, àti kìnìún.

Gbogbo ìlú ló máa ń yìn ín.

Ọdẹ́rìndé di olú-ọdẹ ìlú Owódé.

| | |
|---|---|
| ■ | ÙN Ùn ÌN Ìn ÍN Ín |
| ● | yìn rìn sìn kín |
| ▲ | akínkanjú Ọdẹ́rìndé ìrìn ìyìn |

## Ẹ̀kọ́ 3









## Ẹ̀kọ́ 4











Àgbẹ̀ ni bàbá Tàlà.
Wọ́n fi ọmọlanke kó iṣu lọ sọ́jà.
Gbénga ra iṣu lọ́wọ́ bàbá Tàlà.
Gbénga kó iṣu lọ sí ilé.
Bímpé ìyàwó Gbénga se iṣu náà.
Wọ́n fi ọbẹ̀ panla jẹ iṣu.

| | |
|---|---|
| ■ | N n M m |
| ● | n m |
| ▲ | Gbénga ọmọlanke Bímpé panla gẹngẹ |

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2







Ọ̀rẹ́ ni Yínká àti Bámbọ̀.
Yínká lọ sí oko Bámbọ̀ lọ́jọ́ kan.
Ó bá Bámbọ̀ ro oko.
Yínká àti Bámbọ̀ gbin iṣu àti ẹ̀gẹ́.
Irè oko náà ṣe dáradára.
Yínká àti Bámbọ̀ wá yan fanda.

| | |
|---|---|
| ■ | N n M m |
| ● | n m |
| ▲ | Bámgbóṣé fanda Bámbọ̀ konko Arábámbí |

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4





# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ____________________

**Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà**

**Ìpín 1: Lẹ́tà**
m an ÌN n UN ọn

**Ìpín 2: Sílébù**
kùn gbọn yìn run ṣìn

**Ìpín 3: rọ̀**
òkun Ọdẹ́rìndé Gbénga òfin ẹkùn ràkúnmí

**Ìpín 4: Àyọkà**

Tàfá ní aṣọ ìṣeré mẹ́rin.
Dára láṣọ ìṣeré kan.
Àwọn méjèèjì ni aṣọ eré bọ́ọ̀lù.
Tàfá ni bàtà ìgbábọ́ọ̀lù kan.
Dára fún Tàfá ní bàtà ìgbábọ́ọ̀lù kan.
Tàfá náà fún Dára láṣọ ìṣeré kan.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**
**Ìbéèrè:**

1. Aṣọ eré mélòó ni Tàfá ní?
2. Dárúkọ ohun èlò méjì tí à ń lò fún eré bọ́ọ̀lù?
3. Kí ni Dára fún Tàfá?

**Ìpín 6: Àpèkọ**
ìrìn fanda ẹ̀fọn ikún

**Àríwísí Olùkọ́:**



# Sáà 3

# Ọ̀sẹ̀ 1 - 10




Ìyá Tárá lọ sí ọjà.

Ìyá Tárá ra àpò ìrẹsì ńlá kan.

Ó ra iṣu ńláńlá mẹ́ta.

Ó tún ra nǹkan ìpanu.

Tárá se ìlajì iṣu ńlá kan.

Tárá àti Láńre jẹ iṣu náà.

Tàlà fi epo bíńtín jẹ iṣu tirẹ̀.

Fífi epo jẹ iṣu dùn púpọ̀.

■ Ń ń Ǹ ǹ ẸN ẹn

● ń yẹn

▲ ńlá ńláńlá bíńtín ìyẹn

**Ẹ̀kọ́ 1**





## Ẹ̀kọ́ 2







Tàlà fẹ́ràn oúnjẹ ìbílẹ̀.

Ìdí nìyẹn tó fi ń jẹ iyán.

Ó tún fẹ́ràn gbogbo oúnjẹ tí a fiṣu ṣe.

Tàlà máa ń mu ọsàn fi rẹ ọ̀ǹgbẹ.

Tàlà fẹ́ jẹ ẹran agílíǹtí.

Ó ra ẹran agílíǹtí tó fi sebẹ̀.

Tàlà fọbẹ̀ ẹran agílíǹtí jẹ iyán.

Oúnjẹ náà dùn púpọ̀.

Ń ń Ǹ ǹ ẸN ẹn

ń ǹ yẹn

agílíńtí òǹgbẹ nìyẹn

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4







Làḿbẹ́ gbin ọsàn àti máńgòrò.
Ó tún gbin ọ̀gẹ̀dẹ̀ àti iṣin.
Ìbẹ́pẹ náà pọ̀ ní oko Làḿbẹ́.
Ẹfọ̀n bẹ̀ǹbẹ̀ ń jẹ àwọn èso náà.
Bímbọ́ bá Làḿbẹ́ ra páńpẹ́ lọ́ja.
Làḿbẹ́ dẹ páńpẹ́ fún ẹfọ̀n.
Ẹfọ̀n kò jẹ èso oko Làḿbẹ́ mọ́.

| | |
|---|---|
| ■ | Ḿ ḿ M̀ m̀ Ọ̀N ọ̀n |
| ● | wọ̀n fọ̀n ḿ m̀ |
| ▲ | ẹfọ̀n Bímbọ́ Làḿbẹ ìwọ̀n |

## Ẹ̀kọ́ 1









## Ẹ̀kọ́ 2







Bàbá Tàlà fẹ́ jẹ ẹran-ìgbẹ́ àti àpọ̀n.

Tàlà dẹ pańpẹ́ sínú oko etílé.

Pańpẹ́ rẹ̀ mú ọ̀yà ńlá kan.

Ìyá Tàlà fi ẹran-ìgbẹ́ se ọbẹ̀ àpọ̀n.

Bàbá Tàlà fi ọbẹ̀ àpọ̀n náà jẹ àmàlà.

Ìyá Tàlà àti Tárá jẹ nínú oúnjẹ náà.

Wọ́n jẹ oúnjẹ náà ní àjẹgbádùn.

| | |
|---|---|
| ■ | Ḿ m M̀ m Ọ̀N ọ̀n |
| ● | ḿ m̀ wọ̀n pọ̀n |
| ▲ | gọ̀m̀bọ́ páḿpẹ́ àpọ̀n àwọ̀n |

**Ẹ̀kọ́ 3**









# Ẹ̀kọ́ 4







Iṣẹ́ àgbẹ̀ ni iṣẹ́ bàbá Tárá.

Bàbá Tárá fẹ́ ṣe ọdún iyán.

Tàlà àti bàbá wú iṣu lóko.

Bàbá ra aṣọ àrán fún Tàlà àti Tárá.

Tàlà àti Tárá fẹ́ràn aṣọ àrán.

Bàbá ránṣẹ́ pe onílù.

Onílù lu gángan.

Inú Tàlà àti Tárá dùn.

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| ■ | ÁN án | ÀN àn | Ẹ́ ẹ́ | |
| ● | rán | ràn | ṣẹ́ | gán |
| ▲ | àrán | fẹ́ràn | ránṣẹ́ | gángan |

## Ẹ̀kọ́ 1









## Ẹ̀kọ́ 2











Bàbá-àgbà sọ ìtàn Olóòlù.

Tàlà àti Tárá ni bàbá-àgbà sọ̀tàn fún.

Olóòlù jẹ́ eégún ńlá ní Ìbàdàn.

Àsìkò ọdún ìbílẹ̀ ni Olóòlù máa ń jáde.

Olóòlù máa ń jáde ní ọ̀sán.

Olóòlù máa ń jó.

Ó sì máa ń ṣètùtù fún ílú.

Tàlà àti Tárá fẹ́ràn ìtàn Olóòlù.

| | |
|---|---|
| ■ | ÁN án ÀN àn Ẹ́ ẹ́ |
| ● | sán tàn ràn fẹ́ |
| ▲ | Ìbàdàn ìtàn fẹ́ràn ọ̀sán |

## Ẹ̀kọ́ 3









## Ẹ̀kọ́ 4







Ọdún eégún Agbọ́n ti súnmọ́lé.

Oyin ni wọ́n fi ń ṣe ọdún Agbọ́n.

Oyin máa ń wọ́n lásìkò ọdún Agbọ́n.

Àwọn àpọ́n ti ń ra oyin sílé.

Eégún Agbọ́n máa ń jó kiri lọ́jọ́ ọdún.

Àwọn àpọ́n máa n fún un ni oyin.

Eégún Agbọ́n yóò sì gbàdúrà fún wọn.

| | |
|---|---|
| ■ | Ọ́ ọ́ Ọ́N ọ́n |
| ● | tọ́ pọ́n gbọ́n |
| ▲ | àpọ́n agbọ́n ẹ̀gbọ́n itọ́ |

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2







Eégún Apọ́nrọ́rọ́ kọjá lójúde àwọn Tàlà.

Tárá àti Tàlà wá wòran eégún.

Eégún Apọ́nrọ́rọ́ rí Tàlà àti Tárá.

Tárá fi ọgbọ́n sáré wọ inú ilé.

Tàlà náà sáré tẹ̀lé Tárá.

Eégún wọnú ilé àwọn Tàlà.

Òbí Tàlà fún eégún lówó.

Eégún náà sì súre fún wọn.

| | |
|---|---|
| ■ | Ọ́ ọ́ Ọ́N ọ́n |
| ● | rọ́ wọ́ pọ́n gbọ́n |
| ▲ | Apọ́nrọ́rọ́ ọgbọ́n ọwọ́ ẹ̀gbọ́n |

**Ẹ̀kọ́ 3**





## Ẹ̀kọ́ 4





# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́: ____________________

**Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà**

**Ìpín 1: Lẹ́tà**
ǹ ẹn Ḿ án Ọ́ Ọ̃N

**Ìpín 2: Sílébù**
fọ̀n gbọ́n m̀ ṣé yẹn ń

**Ìpín 3: rọ̀**
Bémbé ẹ̀gbọ́n Ńlańlá pámpẹ́ agílíntí fẹ́ràn

**Ìpín 4: Àyọkà**

Iṣẹ́ àgbẹ̀ ni iṣẹ́ bàbá Tárá.
Bàbá Tárá fẹ́ ṣe ọdún iyán.
Tàlà àti bàbá wú iṣu lóko.
Bàbá ra aṣọ àrán fún Tàlà atí Tárá.
Tàlà atí Tárá fẹ́ràn aṣọ àrán.
Bàbá ránṣẹ́ pe onílù
Onílù lu gángan.
Inú Tàlà àti Tárá dùn.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**
**Ìbéèrè:**

1. Kí ni iṣẹ́ bàbá Tárá?
2. Kí ni wọ́n fẹ́ fi iṣu ṣe?
3. Kí ni ìdí tí inú Tàlà àtí Tárá fi dùn?

**Ìpín 6: Àpèkọ**
Àwọn àpọ́n ti ń ra oyin sílé.

**Àríwísí Olùkọ́:**




Ọjọ́ kẹfà oṣù kẹfà ṣe pàtàkì fún Tárá.

Ọjọ́ kẹfà oṣù kẹfà lọjọ́-ìbí Tárá.

Ọjọ́ yìí tún ṣe pàtàkì fún Tàlà.

Ọjọ́ kẹfà oṣù kẹfà lọjọ́-ìbí Tàlà.

Ọjọ́ kẹfà oṣù kẹfà lọ́dún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.

Ọjọ́ kẹfà oṣù kẹfà fún tẹ̀gbọ́n-tàbúrò.

Ọjọ́ ayẹyẹ àtìgbádùn nínú ẹbí

Ni ọjọ́ kẹfà oṣù kẹfà.

## Ẹ̀kọ́ 1






## Ẹ̀kọ́ 2








Olùkọ́ kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nípa òdiwọ̀n.

Ohun gbogbo la ní òdiwọ̀n fún.

Òdiwọ̀n wà fún ìwúwo àti ìjìnnàsí.

Òdiwọ̀n tún wà fún ìkún àti iye nǹkan.

A lè fi abọ́ tàbí garawa ṣe òdiwọ̀n.

A tún lè lo ẹ̀rọ òdiwọ̀n láti wọn nǹkan.

Inú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ dùn fún ẹ̀kọ́ yìí.

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4







Ọjọ́ Àìkú ni Tàlà máa ń lọ aṣọ ilé-ẹ̀kọ́.

Tàlà máa ń tètè dé ilé-ẹ̀kọ́ lọ́jọ́ Ajé.

Tàlà kì í pẹ́ ní ọjọ́ Ìṣẹ́gun.

Ọjọ́rú ni wọ́n máa ń ṣe iṣẹ́-ọwọ́.

Ọjọ́bọ̀ wà fún ṣíṣe eré ìdárayá.

Ọjọ́ Ẹtì sì ni ìsinmi òpin ọ̀sẹ̀ bẹ̀rẹ̀.

Tàlà máa ń lọ sì ọjà Àbáméta.

# Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2








Ọjọ́ kẹwàá oṣù Igbe jẹ́ ọjọ́ Àìkú.
Ọjọ́ yìí ni ayẹyẹ ọjọ́-ìbí Tàlà.
Ọjọ́ Àbámẹ́ta ni wọ́n lọ rẹran.
Wọ́n pa ẹran náà lọ́jọ́ Àìkú.
Ayẹyẹ ọjọ́-ìbí ni wọ́n fi ẹran ṣe.
Tàlà gbé oúnjẹ lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ ní ọjọ́ Ajé.
Ó pín in fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ẹgbẹ́ rẹ̀.

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4







Fóònù Bàbá Dára bàjẹ́.

Bàbá Dára nílò fóònù alágbèéká.

Bàbá Dára ra fóònù alágbèéká tuntun ní ọjà.

Bàbá Dára nílò fóònù alágbèéká fún òwò rẹ̀.

Àwọn oníbàárà Bàbá Dára pe fóònù rẹ̀.

Láti wá fi mọ́tò kó ìṣu tí wọ́n rà.

Òwò Bàbá Dárà ń gbèrú sí i.

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2








Gbádé ṣe ọjọ́ ìbí.
Gbogbo ẹbí àti ọ̀rẹ́ ni wọ́n péjú pésẹ̀.
Bàbá Tárá ra kọ̀m̀pútà fún Gbádé.
Kọ̀m̀pútà ni wọ́n fi ṣe ẹ̀bùn fún Gbádé.
Inú Gbádé dùn fún ẹ̀bùn pàtàkì yìí.
Gbádé sì dúpẹ́ lọ́wọ́ Bàbá Tárá.
Gbádé ń lo kọ̀m̀pútà yìí fún ẹ̀kọ́ rẹ̀.

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4







Bàbá Tárá ra kọ̀mpútà fún Tárá
Inú Tárá dùn púpọ̀ fún ẹ̀bùn pàtàkì yìí.
Tárá fi kọ̀mpútà han àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀.
Àwọn ọ̀rẹ́ Tárá bá a yọ̀ fún ẹ̀bùn yìí.
Gbogbo wọn ṣeré bọ́ọ̀lù lórí kọ̀mpútà.
Inú Tárá àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ dùn.
Tárá àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ dúpẹ́ lọ́wọ́ bàbá.

## Ẹ̀kọ́ 1





## Ẹ̀kọ́ 2







Àsìkò ìsimi àrun kòrónà ni.

Ìsimi náà pẹ́ púpọ̀.

Tàlà àti Tárá banújẹ́ fún ìsimi yìí.

Àwọn olùkọ́ ṣe ìpàdé lórí ìsimi náà.

Wọ́n pinnu láti fi súùmù kẹ́kọ̀ọ́.

Wọ́n lo súùmù lórí kọ̀ǹpútà.

Inú olùkọ́ àti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ dùn.

## Ẹ̀kọ́ 3





## Ẹ̀kọ́ 4





# Ìwé Aṣàyẹ̀wò

Orúkọ akẹ̀kọ̀ọ́ ____________________

**Iye ìdáhùn tí ó tọ̀nà**

**Ìpín 4: Àyọkà**

Ọjọ́ kẹwàá oṣù Igbe jẹ́ ọjọ́ Àìkú.
Ọjọ́ yìí ni ayẹyẹ ọjọ́-ìbí Tàlà.
Ọjọ́ Àbámẹ́ta ni wọ́n lọ rẹran.
Wọ́n pa ẹran náà lọ́jọ́ Àìkú.
Ayẹyẹ **ọjọ́-ìbí** ni wọ́n fi ẹran ṣe.
Tàlà gbé oúnjẹ lọ sí **ilé-ẹ̀kọ́** ní ọjọ́ Ajé.
Ó pín in fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ẹgbẹ́ rẹ̀.

**Ìpín 5: Kíka Àkàyé**

**Ìbéèrè:**

1. Ta ni ó ń ṣe ayẹyẹ ọjọ́-ìbí?
2. Kí ni ìdí tí Tàlà fi gbé oúnjẹ lọ sí ilé-ẹ̀kọ́?
3. Oṣù wo ni ìwọ máa ń ṣe ayẹyẹ ọjọ́-ìbí rẹ?

**Ìpín 6: Àpèkọ**

Òdiwọ̀n tún wà fún ìkún àti iye nǹkan.

**Àríwísí Olùkọ́:**

— Not for Sale —

PBYP2